Appointment vacant

1. Journey Man Printer
1. Advanc· Printer

Apply
Modupe Press
16 Bamgbose St
Lagos.

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

NOTICE

For urgent Sale!
'CROPPER' Printing Machine with Electric Motor and Starter. 3 Rollers & 2 Chases £200, or Nearest offer, We are selling it because of space for another New Machine.
Write or Call:-
Ire-de Printing Works
9, Massey Street
LAGOS.

VOL. IIII No. 155 MONDAY JUNY 11 — JULY 17 1960 KOBO KAN (1d)

# Itan nla sele ni ile Oluyole, Oni Ife gboye Gomina

ONIROHIN "IROHIN IMOLE"

IBADAN. ỌJỌ ẸTI:- O ṢE OJU MI LONI NI ILU NLA YI TI A NPE NI IBADAN, TABI TI ỌPỌLỌPỌ ẸNYIN ỌMỌ ODUA MỌ GẸGẸBI ILE OLUYOLE, TI EMI PẸLU SARAKI ENIA, ATI AWỌN ONIROHIN ẸLẸGBẸ MI PẸLU ỌGỌRỌ ENIA TI O LE NI ADỌTA ỌKẸ LERUGBA FI OJU ARA WA WO ITAN NI ṢIṢẸ. BI GBOGBO WA TI DURO ni gbangba iwaju ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Kabiyesi Alaiyeluwa Ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ti Ile—Ifẹ jade lati wo awọn ọmọ ogun Ilẹ Naijiria ti wọn to si iwaju ile Aṣofin fun ẹyẹ ati wiwo rẹ gẹgẹbi Gomina titun ti Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ki o to di wipe Alaiyeluwa Aderẹmi yan jade ni a ti ṣe eto ibura rẹ ninu Ile Aṣofin loju awọn Saraki ti Ipinlẹ Iwọ Orun ati ti gbogbo Apapọ Naijiria. Kabiyesi Aderẹmi ẹniti o jẹ adọrin ọdun (ki Edumare lọrẹ ẹmi rẹ ki o pẹ fun wa ki igba rẹ san wa amin o) ni o gba ipo Ọlọla John Rankine ẹniti o fi aye Gomina silẹ ni arin ọsẹ tokọja ki o to di pe o di Gomina, Baba ẹgbẹ Igbimọ Ọba ati awọn Ojoye ni Ọni nṣe.



Oṣi ku wakati mẹrin ti ao ṣe eto ifi Gomina jẹ ni ogunlọgọ enia ti wọn wọ aṣọ daradara ti pejọ si Agodi

Wo Oju Ewe Kẹfa

## Enia meta l'oku bamubamu nibi ija Nepu ati N. P. C. ni Shagamu

SHAGAMU. Enia mẹta lo lọ ie ipe Ọlọrun ni Sabo nihin nigbati ija kan bẹ silẹ larin awọn ẹgbẹ NEPU ati N.P.C, ni alẹ ọjọ Ọjọru ti ọsẹ tokọja. O to wakati meji ti ija na fi nṣe ranyin-ranyin, ki o to di wipe o rọlẹ

Awọn ti a gbọ pe wọn gun pa pẹlu Ọbẹ ni Dan Fulani (ẹni ogun ọdun) Shuaibu Wudele (ẹni ogun ọdun) ati Tasiu Kano (ẹni ọdun mẹrinlelogun) Awọn Hausa ni o ba ara wọn ja ija na Ṣugbọn a ko mọ daju ohun ti o fa ija na Onirohin wa kan fi ye wa pe ariyanjiyan akitiyan ọrọ iṣelu ni on lero pe o fa ija wa larin wọn.

Awọn ti a mọ pe o fi ara gbọgbẹti ọgbẹ na pọ tobẹ tojẹ wipe ọwọ Ọlọrun ni ẹmi wọn wa ti a si nṣe itọju wọn ni Ile Iwosan nihin ni Uba-Ibrahim, Ado-nla Lawal, ati Bala Sawaba, Ṣugbọn sibẹ awọn Ọlọpa gba pe ọpọlọpọ lo fi ara pa ti wọn ko fẹ yọju si gbangba.

Ki ija nla yi to rọlẹ awọn Ọl pa pẹlu ibọn lọwọ lati Ijẹbu-Ode pẹlu Ibandan lo wa tu wọn ka, ọpọlọpọ ohun ẹri gẹgẹbi ọhun gbogbo ti ẹjẹ ti ta si ni awọn Ọlọpa ko lọ. Awọn Ọlọpa inu lati Ibadan bẹrẹ si ṣe ibere ati iwadi lati ẹnu awọn enia nihin lati ọjọ Satide, abayọri ibere, won ni a ko ti mọ. Ni Sabo papa awọn Ọlọpa onibọn lo nṣọ gbogbo ibẹ tobẹ gẹ to jẹ wipe ọja tita ati rira ko fi si ni Sabo.

Ọga awọn Ọlọpa fun Ijẹbu ati Igberiko rẹ Ọgbẹni E. A. Olawaiye fi ikede kan sode ti o lo bayi:

Ni dede agogo mejọ abo ija kan ṣelẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ NEPU ati N.P.C. ni Shagamu ninu eyiti awọn enia mẹta fi ku. Ọpọlọpọ lo si fi ara pa ti wọn si nṣe itọju wọn ni ile Iwosan.

Ọpọlọpọ awọn ọdaran kẹ re ni ọwọ ti ba, ti wọn si wa ni abẹ abo awọn Ọlọpa,

## Adele ki ise Onile Emi Elias

ONI MỌTO (BUS) PUPỌ KAN L'EKO ALHAJI A. W. ELIAS, SỌ FUN ILE ẸJỌ GIGA NI ỌJỌ ẸTI PE ON KO GBA ỌBA MUSENDIKU ADELE NI ONILẸ ON NIPA TI ILE TI ON FI NKO BUS SI NI 67, GREAT BRIDGE STREET L'EKO

Alhaji Elias nṣe idahun si ibere kan ti agbẹjọro Ọba Adele Oloye H. O. Davies Q. C. nbi nigbati wọn wọ ẹjọ ti Ọba Adele pe Alhaji Elias pe ki o wa fi ilẹ ti Opopo Great Bridge silẹ. Alhaji Elias sọ wipe ilẹ na ti Ọba Adele pe on lẹjọ lori rẹ jẹ ilẹ awọn ọmọ idile Ọba Dosunmu, atipe ati kekere ni on ti mọ ilẹ na. Idahun rẹ si ibere imiran ẹlẹri Alhaji Elias sọ wipe on ko le ranti pe boya Ẹgbẹ ilu lo fun on ni ilẹ na lo



OBA ADENIJI ADELE KEJI

ni fun igba diẹ tabi ki on ma lo lọ titi. Ṣugbọn o ni Ọba Adele sọ fun on pe on ti gbe ilẹ na dogo, ṣugbọn ko sọ iye owo ti on gba fun idogo na,

Alhaji Elias ti o sọ wipe on ni ọgbọn Bus, mọto ayọkẹlẹ meje, ati ọkọ nla marun, o kọ jalẹ ohun ti lagbẹjọro Ọba Adele wi fun pe lati ọdun 1950 ni on ti fẹ kọ ibuṣọ fun awọn moto ni Isọlọ. Otitọ ọrọ gan nipe emi ko ni imọran ati kọ irufẹ ibuṣọ bẹ. Nigbati o tun ndahun ibere miran Alihaji Elias ni on ko ni ibuṣọ mọto miran ju eyi to wa ni opopo Great Bridge lọ.

## Ọrọ Isiri fun gbogbo Obinrin!

Lati Ọwọ:- AYỌKA (Lagos)

KIN NTO BẸRẸ IWE si ẹnyin Obirin ẹlẹgbẹ mi ni ọsẹ yi o yẹ kin kọkọ tọrọ aforiji nitori mo ti ṣẹ gbogbo yin, nipapẹ emi ko kọwe tabi bayin fi ọrọ wẹ ọrọ lati ọsẹ tokọja, ohun ti o fa eleyi ni wipe o ṣe mi bi arẹ ni, kiṣe pe Olotu "Irohin Imọlẹ" ko fi aye mi silẹ. Nitorina mo bẹ gbogbo yin ki ẹ ma binu rara o, ara gbogbo wa a lokun o, emi na ko dẹ ni sarẹ mọ o.

Iyẹn bẹ mo rope ori ẹkeji re ti iwe mi si ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ma jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ o dẹ jẹ ero Olotu ati t'emi pe ọsọsẹ ni ki iwe fun imọran fun awa Obirin ma jade, nitori idi eyi, aye wa fun ẹyin na lati kọwe ranṣẹ si mi, iba ṣe ibere ni, iba ṣe alaye ni, kosi eyi ti mo kọ didun inu mi ni gbogbo rẹ yio jẹ, ọkan toku ti ngo bayin sọ ki nto bẹrẹ ọrọ isiri mi nipe, mo bẹ yin ẹ ba mi fi iwe isọpẹ ranṣẹ si Ọgbẹni E. A. Adeniji Olotu Irohin Imọle fun aye ti o si fun awa Obirin, nitoripe kosi Iwe Irohin ni ede karọ'o jire ti ṣe eleyi. Irohin Imọlẹ nikan lo kọkọ ṣe bẹ.

Fi Iwe rẹ ranṣẹ si:- AYỌKA c/o. Irohin Imọlẹ. 16, Bamgboṣe Street Lagos.

### ỌRỌ IṢIRI TI ỌSẸ YI

Ọrọ iṣiri ti emi Ayọka yio sọ ni ọsẹ yi ni nipa ọna ti ija koni saba fi wa larin ọkọ pẹlu aya. Ọrọ mi na koni pọ tobẹ bẹni nko ni sọ itan kankan pẹlu ṣugbọn ngo o sọrọ yi ni asọye.

Ha! iwọ Iyawo ti ọkọ gbe sile, ma ma ṣe bi ti awọn Oloyinbo ti wọn ro pe awọn pẹlu ọkọ awọn jẹ ẹgbẹ (ki iṣe tọjọ ori) iṣẹdalẹ Oyinbo yatọ si tiwa, ni ọdọ awa karọ-o-jire, Ọkunrin ni olori, on ni baba ile tabi bale, ọrọ rẹ ninu ile jẹ aṣẹ ni, igbakeji Ọlọrun lọdọ aya rẹ, Iṣẹdalẹ tiwa niyen Bibeli mimọ ati Alukurani mimọ dẹ tun gbe iṣẹdalẹ wa yi kẹṣẹ bi ko ba da yin loju ki ẹ lọ bere lọwọ awọn Alufa ẹsin yin, kiṣe emi Ayọka ni ngo sọ fun yin, ṣugbọn o dami loju gedegbe pe Bibeli ati Alukurani tọkasi bayi Ibiti awọn kan ninu wa tiri pe ọgbọgba ni tọkọ-taya jẹ ni ko ye mi ki o to di wipe wọn afẹ maṣe kanrangban si ọkọ wọn nile.

Ti iwọ gẹgẹbi iyawo tabi ti o mọ ara rẹ ni iyale ba ti mọ ni ọkan rẹ ti o si n'han ninu iwa rẹ pe ọkọ rẹ ni Olori rẹ, koni si ọrọ kanrangbọn tabi ija, nitoripe wa ma tẹriba fun u, oun na ti ki ba ṣe aṣiwere enia yio ma ni ifẹ rẹ siwaju ati siwaju to jẹ wipe ọpọlọpọ enia lo ma ro pe o fun u ni ogun ifẹ jẹ. Ṣugbọn iwọ ti Ọkọ fẹ si ile ti o lero pe iwọ pẹlu rẹ l'ẹgbẹ, ti o jẹ kanrangbọn ni ẹ jijọ nṣe lojojumọ ki lo lero wipe yio gbẹhin rẹ fun yin. Iwọ oponu ayirada Obinrin iwọ ko mọ pe ọkọ rẹ ni Olori rẹ atipe o gbọdọ ma tẹriba fun.

Kosi ọna miran ti o le fi tẹ ọkọ lọrun ju wipe ki o le tẹriba fun un lọ, ti o ba ntẹriba fun ọkọ ti o ba jẹ aṣiwere enia ti o nfi iwa buruku san rere fun ọ fi silẹ ni Ọlọrun wi, iya rẹ wa ni ọdọ Ọlọrun. Ni ọsẹ to mbọ lagbara Edumare ngo sọrọ lori iwa ti o yẹ ki ọkọ ma hu si aya rẹ, ṣugbọn boya a le ri ọkunrin ti o jẹ bale, ti o le ran mi lọwọ lati kọ nipa iwa ti o yẹ ki ọkọ ma hu si aya. Ti mo ba ri inu mi yio dun mo dẹ fẹ ri iwe na gba ni ọjọ ọjọru ti ṣe Wednesday 13th July 1960. Mo ro pe koni da ṣaka lẹnu mi gẹgẹbi Obinrin lati sọrọ lori iwa ti oyẹ ki ọkọ ma hu si aya. Odigba o emi Ayọka nrale mo lero pe ẹ gbadun ọrọ mi tọsẹ yi ki Oluwa ṣọ pade wa.

## Ọba kan pẹlu awọn Iyawo rẹ meje

Lati ọwọ:— Phillips Olu. Adeniyi

Ni igba kan Ọba kan wa, Ọba na jẹ Ọlọla o ni owo, Ọla ati nkan alumọni gbogbo. Ọba na fẹ Iyawo meje. Ninu awọn iyawo meje yi, awọn mẹfa ni ehin. wọn njẹ ẹran ti o dara. Ṣugbọn ikan ti o ku ko ni ehin. Onjẹ rẹ ni ẹdọ ati ẹja tutu Ko le jẹ ẹran nitoripe ko ni ehin. Awọn mẹfa yi fẹran ara wọn. Nwọn korira ikan ti o ku. Gbogbo wọn nfẹ ojurere ọkọ wọn.

Ni ọjọ kan eyiti o jẹ Iyale ninu wọn lọ ba ọkọ wọn oni Kabiyesi Ọba. O ni Ọba ko dara lati ma tilẹ fi nkan kan han yin ninu onkan ara wa yi. Ibẹ ... ti b e r wipe Ọba iyẹn ni wipe ẹ ko tilẹ ṣe akiyesi gbogb awa iyawo yin lati ọjọ yi. E ko tilẹ mọ wipe n i n awa iyawo yin ọkan wa ti ko ni ehin. He! He! He ni iyawo Ọba yi rẹrin. Oni ẹyin sọ wipe ki a wa ehin han yin ni ọjọ kan. Beni Ọba ba pe gbogb awọn Iyawo rẹ jọ. O wi fun gbogbo wọn wipe, ni ọj meje ni oni, ni enikankan yin ma fi ehin yin han hi on. Eyi ti ko ni ehin ba nronu kakiri. o fẹ rẹ ku nitori pe Ọba ti ni eniti ko ba ni ehin pipa ni won yio p Ki a ma fa ọrọ gun lọ mọ gbogbo onikaluku wọn b nyọ. Nwọn nfi eyi ti ko ni ehin ṣe yẹyẹ

Ni ọjọ kan eyi ti ko ni ehin ba mu ọna oko p ọ n nigbati o nlọ ni o ba ri Okete kan Okẹte yen wo Obi nrin yi titi anu Obinrin yi ba ṣe Okete yi lilanu ẹ Okete yi lano Obinrin yen kan so lọ pẹlu ironu rẹ. C ku ọjọ mẹta ti wọn ni lati lọ fi ehin wọn han Ọba.

Bi Obinrin yi kan ṣe nsalọ ni o ba ri kukute igi ka Obinrin yi ba sọkun ba o ni iwọ igi yi njẹ o le iranlọwọ kan fun mi? Igi yẹn ba da lohun kan wip anu eyikeyi ti iwọ ba nfẹ ni emi le ṣe fun ọ. Igi yi b wi fun Obinrin yi wipe:- Iru anu wo ni o tilẹ nfẹ na Obinrin yi ba ro gbogbo ọjọ fun Igi ba sọ fun wip ki o ma sọkun mọ o ni on yio ṣe iranlọwọ ra fu Igi yẹn ba wi fun Obinrin yi wipe ahọn rẹ ni a ma l fun nkan ti a fẹ ṣe yi igi na ba bere lọwọ rẹ wip Iwọ Obinrin yi ṣe o le roju rẹ? Obinrin yi ba ni, bi tilẹ jẹ pe o ma pa on ni on a roju, ki a ma fa or gun lọ titi igi yi ba mu ọbẹ o fi ge ahọn obinri yi o ni ki o mu ahọn yi ki o din dada oni ti ba de ile, oni Iyale rẹ kan wa, oni on yio kọk bere wipe Ah! Iyawo mi kini nkan o mu wa fun wa O ni ki o fun ni ahọn yi ti ẹkọ kan o ni ti o b jẹ, o ni gbogbo ehin rẹ a danu lẹnu rẹ, inu obinri yi ba bẹrẹ si ni dun o dupẹ lọwọ igi yi dada. Ni gbati o de ile oju iyale rẹ ti wo eran yi o ni Iyaw mi kini nkan ti o mu wa fun ni Obinrin yi ba fu ni ẹran yi ati ẹkọ Iyale rẹ yi ba jẹ. Nigbati Iyal rẹ fẹ lọ da ewe ẹkọ, nu nṣe ni gbogbo ehin rẹ dan

WO IYOKU NI OJU EWE KẸRIN

A O SI LAIPE YI

Pep-Si-Cola
Fun asayan re

O TUTU. O SI TUNI-LARA

ILE ISE NLA
MUSHIN

## Ọrọ Isiri fun gbogbo Obinrin!

Lati Ọwọ:- AYỌKA (Lagos)

KIN NTO BERE IWE si ẹnyin Obirin ẹlẹgbẹ mi ni ọsẹ yi o yẹ kin kọkọ tọrọ aforiji nitori mo ti ṣẹ gbogbo yin, nipape emi ko kọwe tabi bayin fi ọrọ we ọrọ lati ọsẹ tokọja, ohun ti o fa eleyi ni wipe o ṣe mi bi arẹ ni, kiṣe pe Olotu "Irohin Imọlẹ" *ko* fi aye mi silẹ. Nitorina mo bẹ gbogbo yin ki ẹ ma binu rara o, ara gbogbo wa a lokun o, emi na ko dẹ ni ṣarẹ mọ o.

Iyẹn bẹ mo rope ori ẹkeji re ti iwe mi si ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ma jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ o dẹ jẹ ero Olotu ati t'emi pe ọsẹsẹ ni ki iwe fun imoran fun awa Obirin ma jade, nitori idi eyi, aye wa fun ẹyin na lati kọwe ranṣẹ si mi, iba ṣe ibere ni, iba ṣe alaye ni, kosi eyi ti mo kọ didun inu mi ni gbogbo rẹ yio jẹ, ọkan toku ti ngo bayin sọ ki nto bere ọrọ isiri mi nipe, mo bẹ yin ẹ ba mi fi iwe isọpe ranṣẹ si Ọgbẹni E. A. Adeniji Olotu Irohin Imọle fun aye ti o si fun awa Obirin, nitoripe kosi Iwe Irohin ni ede karọ'o jire ti ṣe eleyi. Irohin Imọlẹ nikan lo kọkọ ṣe bẹ.

Fi Iwe rẹ ranṣẹ si:- AYỌKA c/o. Irohin Imọlẹ.
16, Bamgboṣe Street Lagos.

### ỌRỌ IṢIRI TI ỌSẸ YI

Ọrọ iṣiri ti emi Ayọka yio sọ ni ọsẹ yi ni nipa ọna ti ija koni saba fi wa larin ọkọ pẹlu aya. Ọro mi na koni pọ tobẹ bẹni nko ni sọ itan kankan pẹlu sugbọn ngo o sọrọ yi ni asọye.

Ha! iwọ Iyawo ti ọkọ gbe sile, ma ma ṣe bi ti awọn Oloyinbo ti wọn ro pe awọn pẹlu ọkọ awọn jẹ ẹgbẹ (ki iṣe tọjọ ori) iṣẹdalẹ Oyinbo yatọ si tiwa, ni ọ d ọ awa karọ-o-jire, Ọkunrin ni olori, on ni baba ile tabi bale, ọrọ rẹ ninu ile jẹ aṣẹ ni, igbakeji Ọlọrun lọdọ aya re, Iṣẹdalẹ tiwa niyen Bibeli mimọ ati Alukurani mimọ dẹ tun gbe iṣẹdale wa yi kiṣẹ bi ko ba da yin loju ki ẹ lọ bere lọwọ awọn Alufa ẹsin yin, kiṣe emi Ayọka ni ngo sọ fun yin, ṣugbọn o dami loju gedegbe pe Bibeli ati Alukurani tọkasi bayi Ibiti awọn kan ninu wa tiri pe ọgbọgba ni tọkọ-taya jẹ ni ko ye mi ki o to di wipe won afẹ maṣe kanrangban si ọkọ wọn nile.

Ti iwọ gẹgẹbi iyawo tabi ti o mọ ara rẹ ni iyale ba ti mọ ni ọkan rẹ ti o si n'han ninu iwa rẹ pe ọkọ rẹ ni Olori rẹ, koni si ọrọ kanrangbọn tabi ija, nitoripe wa ma tẹriba fun u, o na ti ki ba ṣe aṣiwere enia yio ma ni ifẹ rẹ siwaju ati siwaju to jẹ wipe ọpọlọpọ enia lo ma ro pe o fun u ni ogun ifẹ jẹ. Ṣugbọn iwọ ti Ọkọ fẹ si ile ti o lero pe iwọ pẹlu rẹ l'ẹgbẹ, ti o jẹ kanrangbọn ni ẹ jijọ nṣe lojojumọ ki lo lero wipe yio gbẹhin rẹ fun yin. Iwọ oponu ayirada Obinrin i w ọ ko mọ pe ọkọ rẹ ni Olori rẹ atipe o gbọdọ ma teriba fun.

Kosi ọna imiran ti o le fi tẹ ọkọ lọrun ju wipe ki o le tẹriba fun un lọ, ti o ba nteriba fun ọkọ ti o ba jẹ aṣiwere enia ti o nfi iwa buruku san rere fun ọ fi silẹ ni Ọlọrun wi, iya rẹ wa ni ọdọ Ọlọrun. Ni ọsẹ to mbọ lagbara Edumare ngo sọrọ lori iwa ti o yẹ ki ọkọ ma hu si aya rẹ, ṣugbọn boya a le ri ọkunrin ti o jẹ bale, ti o le ran mi lọwọ lati kọ nipa iwa ti o yẹ ki ọkọ ma hu si aya. Ti mo ba ri inu mi yio d u n mo dẹ fẹ ri iwe na gba ni ọjọ ọjọru ti ṣe Wednesday 13th July 1960. Mo ro pe koni da ṣaka lẹnu mi gegebi Obinrin lati sọrọ lori iwa ti oyẹ ki ọkọ ma hu si aya. Odigba o emi Ayọka nrale mo lero pe ẹ gbadun ọrọ mi tọsẹ yi ki Oluwa ṣọ pade wa.

---

## Ọba kan pẹlu awọn Iyawo rẹ meje

Lati ọwọ:— Phillips Olu. Adeniyi

Ni igba kan Ọba kan wa, Ọba na jẹ Ọlọla o ni owo, Ọla ati nkan alumọni gbogbo. Ọba na fẹ Iyawo meje. Ninu awọn iyawo meje yi, awọn mẹfa ni ehin wọn nje ẹran ti o dara. Ṣugbọn ikan ti o ku ko ni ehin. Onjẹ rẹ ni ẹdọ ati ẹja tutu. Ko le jẹ ẹran nitoripe ko ni ehin. Awọn mẹfa yi fẹran ara wọn. Nwọn korira ikan ti o ku. Gbogbo wọn nfẹ ojurere ọkọ wọn.

Ni ọjọ kan eyiti o jẹ Iyale ninu wọn lọ ba ọkọ wọn oni Kabiyesi Ọba. O ni Ọba ko dara lati ma tilẹ fi nkan kan han yin ninu onkan ara wa yi. Ibẹ ni o ti bẹrẹ wipe Ọba iyẹn ni wipe ẹ ko tilẹ ṣe akiyesi gbogbo awa iyawo yin lati ọjọ yi. E ko tilẹ mọ wipe:- n i n u awa iyawo yin ọkan wa ti ko ni ehin. He! He! He! ni iyawo Ọba yi rẹrin. Oni ẹyin sọ w i p e ki a wa fi ehin han yin ni ọjọ kan. Beni Ọba ba pe g b o g b o awọn Iyawo re jọ. O wi fun gbogbo wọn wipe, ni ọjọ meje ni oni, ni ẹnikankan yin ma fi ehin yin han han on. Eyi ti ko ni ehin ba nronu kakiri, o fẹ rẹ ku nitoripe:- Ọba ti ni ẹniti ko ba ni ehin pipa ni won yio pe. Ki a ma fa ọrọ gun lọ mọ gbogbo onikaluku wọn ba nyọ. Nwọn nfi eyi ti ko ni ehin ṣe yẹyẹ

Ni ọjọ kan eyi ti ko ni ehin ba mu ọna oko p o n, nigbati o nlọ ni o ba ri Okete kan Okẹte yen wo Obinrin yi titi anu Obinrin yi ba ṣe Okete yi Jilanu t i Okete yi lann Obinrin yen kan sa lọ pẹlu ironu rẹ. O ku ọjọ mẹta ti wọn ni lati lọ fi ehin won han Ọba.

Bi Obinrin yi kan ṣe nsalọ ni o ba ri kukute igi kan Obinrin yi ba sọkun ba o ni iwọ igi yi nje o le ṣe iranlọwọ kan fun mi? Igi yẹn ba dahun kan wipe anu eyikeyi ti iwo ba nfẹ ni enii le ṣe fun ọ. Igi yi ba wi fun Obinrin yi wipe:- Iru anu wo ni o tilẹ nfẹ na? Obinrin yi ba ro gbogbo ẹjọ fun Igi ba sọ fun wipe ki o ma sọkun mọ o ni on yio ṣe iranlọwọ na fun. Igi yẹn ba wi fun Obinrin yi wipe ahọn re ni a ma lo fun nkan ti a fẹ ṣe yi igi na ba bere lọwọ rẹ wipe Iwọ Obinrin yi ṣe o le roju rẹ? Obinrin yi ba ni, bi o tilẹ jẹ pe o ma pa on ni on a rọju, ki a ma fa ọrọ gun lọ titi igi yi ba mu ọbẹ o fi ge ahọn obinrin yi o ni ki o mu ahon yi ki o din dada oni ti o ba de ile, oni Iyale rẹ kan wa, oni on yio kọko bere wipe Ah! Iyawo mi kini nkan o mu wa fun wa? O ni ki o fun ni ahọn yi ti ẹkọ kan o ni ti o ba jẹ, o ni gbogbo ehin rẹ a danu lẹnu rẹ, inu obinrin yi ba bẹrẹ si ni dun o dupẹ lọwọ igi yi dada. Nigbati o de ile oju iyale rẹ ti wo eran yi o ni Iyawo mi kini nkan ti o mu wa fun mi Obinrin yi ba fun ni ẹran yi ati ẹkọ Iyale rẹ yi ba jẹ. Nigbati Iyale rẹ fẹ lọ da ewe ẹkọ nu nṣe ni gbogbo ehin rẹ danu

WO IYOKU NI OJU EWE KẸRIN

A O SI
LAIPE YI

Pep-Si-Cola
Fun asayan re

O TUTU. O SI TUNI-LARA

ILE ISE NLA
MUSHIN

OBERE LATI OJU EWE KEJI

lẹnu rẹ. Obinrin ti ko ni ehin ti di eniti o ni ehin o fi ọwọ bo ẹnu rẹ ko jẹki enia kan-kan mọ.

O wa di ọla ti wọn ma fi ehin han ọkọ wọn, ọjọ pe, gbogbo ara ilu joko ati Ọba ati awọn Ijoye. Ekini bọ sita o ba bere si ni fi ehin han gbogbo awọn ti awọn ti wọn joko. O ba bẹrẹ si ni kọrin wipe, Emi aya Laishade Owo, emi aya Laishade Ọsun. Ejirẹ wa iwọ ma sunkun, Ejirẹ wa iwọ ma wuoni. Ki aba Adeji sọrọ ki aba ọkọ sọrọ. Emi a rin ṣẹrẹ Emi a rin keke ngo ba ọkọ mi sọrọ lọwọ. Ekini ṣe bayi.

WO OJU EWE KẸFA

## Akiyesi Pataki

Eyi ni lati kede fun ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ gbogbo ti ẹ kọ owe Idije wa wipe ẹ o ri ka ninu Irohin Imọlẹ ọsẹ to mbọ, eniti ojẹ owo na, ati iru owe ti o pa kio to jẹ owo na o. E mura silẹ lati jẹ Idije miran lẹhin igbati ti owe ba jade tan.

Olotu.

## Oni Motosaikulu yinyin ( Ice )




Ọjọgbọn James Malden ti erekuṣu Falklan ni a ri lori motosaikulu ti o npada bọ si Southampton Hampshire ni England. Ọkọ oju omi John Biscoe lo gbe on pẹlu Triumph motosikulu re gunlẹ lehin igbati o ti lọ gun mọtosaikulu re ni ilu yinyin (Antarctic)

Malden sọ wipe on ni eda alaye ti o kọkọ gun motosaikulu ni ilẹ yinyin ti Antarctic Ọkọ Ọba ti a nfi wadi ohun gbogbo nipa omi ati ilẹ yinyin John Biscoe ati Ọjọgbọn Malden rin ju adọta lerugba ọkẹ ibusọ lọ ki wọn to pada de si England.


ṣile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Ṣile kan pere ni owo rira rẹ, kore ẹgbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, enikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu ọ tabi ọbi rẹ. Mura silẹ.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni ṣile kan kan

'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO

